# ELETI OFE

A-NJU-WON KO SE WI LEJO..

VOL. XIV No. 323 LAGOS SATURDAY JUNE 9. — JUNE 15, 1962 [illegible]


# Oro B'ehin Yo, Okunrin Kan Di Agemo Ninu Ile Ale Re

IBADAN—Erin [illegible] gbogbo awon ti o wa si kotu Ibile Ibadan ni Ijeta nigbati nwon gbo ejo ti awon okunrin meji kan ti awon olopa mu wa siwaju Adajo [illegible] atipe kinni o fa ija ti nwon ja ti o fi di wipe olopa ni lati mu toko-taya wa si Kotu pelu esun wipe nwon fe pa okunrin kan si Ijoba loran.

Oro na lo bayi; odomokunrin kan ti o ti yan obinrin kan ni ore lo si ile re nigbati o ri pe oko re ti lo si ibi-ise, nwon si bo si iyara, nwon ti ilekun mori, nibiti nwon mba ise lo lowo ni oko ba ber si kan'kun.

Gbara ti iyawo ti gbo ohun [illegible] o ni ki ale na bo si abe-eni, o si di agemo. Nigbati oko tu eni na ni ale ba beresi gba [illegible] ki o le ribi salo.

Nigbati iyawo ri wipe [illegible] oko on, ni on na ba ko [illegible] oka [illegible] si luu ni alubole. Adajo Kotu ni ki toko-taya san pomun mewa mewa si apo Ijoba fun ija ti nwon fi je okunrin pansaga na.


# Lagos Citizens
## Rights Protection Council

### Notice

There will be a Divisional Meeting of the LAGOS CITIZENS RIGHTS PROTECTION COUNCIL at the RIALTO CINEMA, Offin R'd., Lagos on Saturday, June 9th, 1962, at 4 P.M.

All members in "A" Ward are cordially invited to attend and be punctual.

**A. T. Ariori**
Hon. Secretary


# Oyinbo Kan Ni Oyinbo Ti O Ba Fe

## Joko Ni Ile Yi, Ki O Mase Fe Obinrin Enia-dudu.

Oyinbo Gesi oloogun kan ti oruko re nje [illegible] Tate ti awon Ijoba ti so wipe awon fe wa a kuro nile yi, so fun Ayiluka 'Eleti-Ofe'' ni ale ana wipe, gbogbo oro na su on, on si ti mura tan nisisiyi lati pada si ilu on, ni ilu Oyinbo, sugbon ki on to lo, on ni ikilo kan ti on fe se fun awon Oyinbo elegbe on ti nwon ko ni iyawo nile, ti nwon si nfe fi obinrin enia-dudu se iyawo.

Nigbati mo pade Ogbeni Tate, omi-ekun fere ma bosile loju re. O ni on fe ki awon elomiran fi oro t'on yi k'ogbon, ti nwon ba ri omobinrin Nigeria ti o wu won, ki nwon jowo ki nwon mase gbee sinu ile; nwon le haya ile fun nibikan nita, ki nwon si maa fun un ni owo onje re losiosu, ki nwon si ma fi oru boju lo si odo re ni alale ti nwon ko ba fe ijogbon.

(Wo yoku loju ewe kejo)

# Awo Irawo

## Eyi ni awon nkan ti yio selo si o ni ose ti o mbo.

AQUARIUS (Jan 22-Feb 20) Fi oju si ọna fun irin-ajo daradara kan. Maṣe jẹ ki ibinu ba nkan jẹ lọdọ rẹ.

PISCES (Feb 21-Mar 20) Ọsẹ ọrọ ṣiṣẹ tabi ọrọ-iyan niyi ṣugbọn ọgbọn inu ni o yẹ ki o fi yanju ọrọ rẹ.

ARIES (Mar 21-April20) Maṣe kọ rara bi ẹnikẹni ba pe ẹ ni ipe kan; masi ṣe ro irokuro.

TAURUS (April 21-May 20) Ṣe ipinnu ti koṣe fi fale, ki o wa duro ki o ma wo'ran.

GEMINI (May 21-June 21) Wa ri ti e ṣe ninu ọrọ-madaru kan lọsẹ yi. Irohin rere wa fun ọ.

CANCER (Jun 22-July 23) Bi o ba mọ eṣẹ gbe daradan wa ṣe orire kan lọsẹ yi nipa owo nina ati iṣẹ ṣiṣe.

LEO (July 24-Aug 22 Wa ọrẹ kun ọrẹ, maṣe fi ẹnikan ṣe ẹlẹya.

VIRGO (Aug 23-Sept 23) Jọwọ maṣe fi oju-mi-to ba nkan jẹ; ti o ba ko a-ba-mọ nkan ti nṣe ọ ni ki o tẹju mọ.

LIBRA (Sep 24-Oct 23) Ki o ni igbagbọ pe gbogbo nkan a yori si rere. Ọpọlọpọ enia ni yio fi oju rere wo ọ.

SCORPIO (Oct 24-Nov 22) Nkankinkan ti kadara rẹ ba muwa ni ki o gba; ṣugbọn olufẹ rẹ kan yio ta ọ lọrẹ ninu ọsẹ yi.

SAGITTARIUS (Nov 23-Dec 22) Wa dojukọ oke-iṣoro kan nitorina ki o tun ba ọrẹ atijọ kan ti ẹ ti ni ifẹ ara yin ṣ'ọrẹ.

CAPRICORN Dec 23-Jan 21) Eyi ni ọsẹ ifarada fun ọmu ọkan kuro ninu pe wa ri ẹnikan ti yio kẹ ọ gẹgẹ.

## Omo Araiye Ko Feni Fe're

(LATI ỌWỌ ABIỌLA BỌLARINWA)

N igba lailai ri, ni Olu ilu kan ni Ila-Orun, ilu yi jẹ ilu kan ti o tobi lọpọlọpọ ti o si jẹ wipe ẹmi awọn ara ilu wọnyi ko fi bẹ balẹ. Igba ki ilọ bi orere, ohun akọkọ ti wọn o kọkọ bojuwo, bojuri ni inu ilu yi ni gbajumọ kan ti o ti jẹ enia nla ri, ni olu ilu yi, awọn ẹmọ araiye si ti bajẹ, o si wa tun jẹ ẹnikan ti o kọ ile mọ'le, ti o si tun kọ aṣẹ mọ a rẹ. Ki Ọlọrun ma jẹki a ri arun ti yio yọ wa ni ẹgbẹ ati lẹgba. Arun ti o yọ arakunrin yi lẹgbẹ a l'ọgba n' arun kan ti awa Yoruba korira julọ, arun ẸTẸ, arun ti iyọ ni ninu ilu lọ si aginju, ti iyọ ni ninu ẹbi, ti iyọ ni ninu ẹbgẹ, ti isi tun mu ni padanu ohun alumọni ati ọrẹ lojiji.

Ah! igbati ọkunrin yi alara paapa ma boju wo-boju ri, okiki yi ti nkan kakiri diẹ, diẹ pe o ti ko arun ẹtẹ yi, on alara ko han si bẹ pe otitọ ni. Ko pẹ, ko jinna, awọn ọrẹ rẹ timọ-timọ wọn ko mọ pe iru nkan bayi wa lara arakunrin wọn, nwọn ba dijọ damure lọ si ibi aṣe iyawo ni ojọ ọjọ ọdun. wọn ba lọ si ode, igbati wọn de ode yi nkọ, gbogbo ohun ti wọn ni lati fi ṣe wọn la l'ejo, nwọn nya tirẹ sọtọ. O wa bere wipe ki lode ti ẹ nfi nya awo temi sọtọ? ọkan ti o laya ti ọrọ ko fo laya lati sọ wa dide, o ni iwọ arakunrin, idiẹ ti a nfi ya awo ati ife tirẹ sọtọ fun ẹ ni wipe bi a ko ba fun ẹ arara a o fẹbi Ọlọrun Ọba ati Enia nitori asiko ti o wa l'aiye ti o si tilẹ tun wa l'oju igba rẹ, adijọ ma ntọwọ-bọwọ ni sugbọn kini nkọ ni asiko yi o ti wa ninu ẹni ti enia ko gbọdọ sun tọ mọ nitori

kini o ti "Dẹtẹ".

Ni ẹsẹ kẹsẹ okiki ti kan lọ ba Ọba ilu yi; igbati ọba paapa gbọ ẹnu ya pe gbajumọ inu ilu yi, ọba ni ye! paga! paga !! sangba fọ, lagbaja yi ni wa di ẹni ti a o wa mu lọ si abule'ko lati lọ ma d'agbe ah! kini ka kamọmọ O! awọn ilu mẹ ara kọ Ebikọ patapata

awọn ọrẹ rẹ ni wọn wa dorikodo wọn sọkun lọpọ-lọpọ, wọn ba gba ara wọn ni mọran pe ki awọn ṣ amaku gbe arakunrin yi lọ si inu aginju lọganjọ oru.

Igbati o ya wọn ba mura lati gbe gẹgẹ bi wọn ti ṣe gba imọran wọn. Igba ti wọn o fi lọ, wọn ra sin

Wo yoku loju ewe kẹjọ

# Alase Ijoba Be Ile Ise Esuu Wo



Ọgbẹni Dennis Vosper, Akowe Isowọpọ Oniṣẹ-ọwọ nilu Oyinbo ni nwọn gbe ladugbo Esuu kan le lọmọ fun ayewo, lasiko ti o lọ bẹ Ile Iṣẹ Iwadi Atako Esu wo nilu nla London.

Igbakeji Alakoso ile iṣẹ na, Dokita P. T. Haskell, ni a nwo aworan rẹ lọwọ osi yi.

**E Polowo Oja Nyin**

**Sinu Iwe Irohin Eleti-Ofe**

# Awon oba fi waya ki

## Alakoso Ijoba Titun

IBADAN — Alakoso Ijọba ipinlẹ Iwọ-orun ti Ijọba Apapọ yan, Dokita Majẹkodunmi, ni nwọn ti da oporo iwe waya bo lati ki ku orire fun yiyan ti a yan lati ṣe akoso ijọba Iwọ-Orun Nigeria.

Alaiyeluwa, Sir Ladapọ Ademọla, Ọba Alake nilu Abẹokuta fi iwe waya ki ku orire ni orukọ gbogbo Ẹgba, o si gbadura ki ibukun Ọlọrun ki o wa pẹlu rẹ ki o fi le ṣe iṣẹ na yori si rere fun ogo Ọlọrun ati ilẹ Ẹgba.

Alaiyeluwa, R. A. Aderele, Tẹwọgboye Keji, Ọba Ondo, gbadura fun iranlọwọ Ọlọwọ fun Alakoso lati le ṣe iṣẹ rẹ yori si rere ni ipinlẹ Iwọ-Orun Nigeria.

Bakanna ni Akonijẹ Ile Igbimọ awọn agba oṣelu, Oloye Dennis Osadebay ki ni orukọ gbogbo awọn Igbimọ agba Oṣelu pẹlu adura fun iranlọwọ Ọlọrun lati fi wẹ ipinlẹ na mọ kuro ninu idamu ati wahala ti iwa buburu nko baa.

Awọn Ọba miran ti o tun ti fi iwe ki Alakoso na ni Alaiyeluwa Ọba Ajalọrun ti Ijẹbu-Ifẹ ati Ọba Jomo ti Irele, ni Okitipupa. Ako le ka ti awọn enia jankanjankan tan, awọn ẹnibi, Alaṣẹ awọn Ọlọpa, Ogbẹni M. A. Ọlanrewaju, Ogbeni Ayọdele Okusaga, Oloye S. O. Obaseki ti ilu Benin.

## Alufa Sosi Kan Pe Awon Ijo Re Lejo Si Kotu

OSHOGBO-GBogbo awọn Ijọ Ṣọsi kan ti wọn npe ni Ijeru Baptist Church ni Ogbomọṣọ ni nwọn pe ṣiba-ṣiba sinu Kotu—nla laipẹ yi lati gbọ ẹjọ ti Alufa wọn ro fun Adajọ lori awọn agba mẹta ninu awọn 'jọ ti o pe l'ẹjọ. Orukọ Alufa na ni Solomon Ige o ni on fẹ gba adọta-lenigba pọnun (£250) lọwọ awọn Ayọ Ayangade, A. Babalọla ati J. A. Ayanlọla fun orukọ on ti nwọn bajẹ.

Nigbati alufa na bẹrẹsi ro ẹjọ rẹ, o ni ninu oṣu May ọdun ti o kọja lọ ni awọn ọkunrin mẹta yi kọ iwe kan si awọn Ijọ Ṣọsi Oke Ijẹru, Ibu Aje, Sodwin ati Molayọ wipe gbogbo owo ti nwọn da fun Ṣọsi ni on ti na fun ara on. O ni irọ ni nwọn pa mọ on.

(Wo yo ku loju ewe karun)

# Baba'sale Egbe Alagbelebu Pupa



Ọba ilu Zanzibar (Sultan) gba lati jẹ Baba'salẹ fun ẹgbẹ Alagbelebu Pupa nilu Oyinbo nigbati Lord Wootton, Alaga ẹgbẹ Alagbelebu Pupa nfi nkan ami ẹgbẹ fun un, ni a nwo ninu aworan yi.

## Aboyun Jale Ni Sosi, O Wewon Odun Kan Abo

ADO-EKITI — Laipẹ yi ni adajọ kotu kan sọ obinrin aboyun kan ti orukọ rẹ njẹ Florence Faderera s'ẹwọn ọdun kan ati abọ nitoripe o ji owo ti awọn ijọ Ṣọsi kan da si Ṣọsi wọn gbe.

Ẹjọ ti awọn ọlọpa ba ọdaran na ro ni pe, lọjọ kan, on ati awọn ọrẹ rẹ meji, Ebun Fọlọrunṣọ ati Esther Fọlakẹ lọ si Ṣọsi C.M.S. Lẹhin nwọn ti ṣe isin tan ni ọdaran na si ṣe ogbọn arekereke ti o gbe apoti ti nwọn ko owo-ọrẹ ọjọ nasi ati idi ọgẹdẹ kan ti ẹnikan wa fi s'ọpẹ f'Ọlọrun lowurọ ọjọ na. Gbogbo owo ninu apoti na jẹ pọnun merinlelogbọn, ṣile mẹrinla ati kọbọ meji.

Adajọ ti o da ẹjọ na ni ki awọn ọrẹ ọdaran meji na maa lọ ni alafia nitoripe on ri wipe wọn ko mọ nkankan nipa ọrọ na.

**E foju S'ona Fun Itan Eko Akete Ile Ogbon Ninu Iwe Wa Ose To Mbo**

ELETI--OFE
ANJUWON KO SE WI L'EJO
EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM
28, Kokoky Street, Lagos. "ELETI OFE," LAGOS
P. O. Box 407 Phone 23330.
VOL XIV. No. 521. SATURDAY JUNE 9, - JUNE 15, 1962.

# Adura L'ebo

NIGBATI ọrọ ba koja ohun ti enia le sagbara le lori lati se ipari rogbodiyan ti o ba bẹ silẹ larin awọn alagbara, (gẹgẹbi ede ti Yoruba maa fi npe awọn enia pataki bi Ọlọla tabi Ọba) ti ina edeaiyede na ba nran lọ nilẹnu perewu, kosi ohun ti awọn mẹkunnu ilu lese ju wipe ki nwọn tẹwọ adura si Ọlọrun Ọba, Olodumare ki o ba wa p'ẹtu si i lọ.

Kosi ohun ti a le fi se iranlowo fun Alakoso ti Ijẹba Apapọsẹ ati fun ipinlẹ Iwọ-Orun ju adura wa lọ, ki a si maa se adura na daradara, ki Ijọba alafia ati asẹ rere le tete pada si ipinlẹ na.

Adura ti awa, Eleti-Ọfẹ ni ki iranlowo Ọlọrun ati ibukun Rẹ, ki o wa pelu Ọlọla Agba Igbimọ, Dokita Majẹkodunmi ati awọn alabasisẹ rẹ ninu isẹ nla ti a gbe le wọn lọwọ.

Adura l'ẹbọ.

# Earl De La Warr, Oloye Nla



Aworan ti a nwo yi niti Earl De La Warr, Oloye nla, ti a ti mọ oruko rẹ gẹgẹbi Herbrand Edward Dundonald Brassey Sackville, ti a bi ninu ọdun 1900. O ti se ọpọlọpọ ọdun ninu isẹ ọba, ki o to wa di Alaga Igbimọ ẹgbẹ ajumọsẹpọ (Commonwealth).

# Iwe si olotu

## Nipa Owo Atijo

A jẹ idunnu mi bi ẹ ba le gba mi laiye ninu iwe-irohin nyin Eleti - Ọfẹ lati kesi awọn alasẹ Ijọba Apapọsẹ wipe asiko ti nwọn fun wa fun ofin owo atijọ ti nwọn fẹ kọkere, ki nwọn jọwọ, ki nwọn bawa fi osu diẹ kun un.

Nitoripe ni ọpọlọpọ awọn ileto ati abule ti o mbe ni Nigeria awọn ẹlomiran ko tilẹ ti gbọ nipa ikilọ yi, owo-atijọ si kun ọwọ wọn nibiti nwọn fi wọn pamọ si.

Atipe Banki (ile-ifowopamọ) jinna si Abule awọn miran. Bi awọn alarẹ Central Bank ba le fi ọsẹ kan se wahala, ki nwọn mu awọn Ọlọpa ti yio gbe ibọn lọwọ ninu mọto ki nwọn si ma ba wọn se owo na kiri abule, a dara pupọ.

Emi ni,

Ilesha A. Opaleye

## Itan Na Dun Pupo

Ẹ ba wa dupẹ lọwọ opitan nyin, Ọgbẹni Ọlalekan Ọnatade fun itan ilu Eko ti o pe ni "Eko Akete Ile Ọgbọn" ti o bẹrẹsi kọ sinu iwe Eleti-Ọfẹ laipẹ yi. Itan na dun pupọ, o si mu mi ranti igba-ewe mi ni ilu Eko ati bi a ti ma nfi ibẹru bojo gun Kereni ti nwọn npe ni Carter Bridge ni aiye atijọ.

Itan Ọgbẹni Ọnatade na tun mu mi niran bi Ebute-Metta ati ọja Oyingbo tiri nigbana. Ẹ jọwọ, ẹ tun ba wa gba opitan yi ni iyanju si, ki o le bawa kọ itan iyoku si.

Olotu, kisẹ awada, a ngbadun iwe Eleti-Ọfẹ.

Emi ni,

Ibadan. Ade Williams

## A Ngbadun Itan Eko Ake te Ile Ogbon

INU mi yio dun pupọ bi Olotu iwe-irohin Eleti-Ọfẹ ba le gba mi laye ninu iwe rẹ oloyinmọmọ lati dupẹ lọwọ Ọgbẹni Ọlalekan Ọnatade fun irohin nipa bi ilu Eko ti ri ni aiye atijọ eyiti o pe ni "EKO AKETE ILE ỌGBỌN" ti o njade l'ọsẹ meji meji si ara wọn.

Itan na dun pupọ, a si ngbadun rẹ; paapa apa ibiti o mu ẹnu kan Lisa ti nse aja ija-gidigbo pelu awon ara Liberia ti a ma npe ni Kurumọ ni Olowogbowo l'Eko ni aiye igbaun, ati bi awọn ọpọlọpọ awọn ara Ikorodu se ba awọn ara Abẹokuta (Ẹgba) ja.

Iwe-itan yi ni iti jẹ nkan ti o le wulo fun awọn ọmọ ile-ẹkọ lẹhin ọla, bi awọn oluko wọn ba le gba wọn niyanju wipe ki nwọn ma ka itan alarin-rin na ninu iwe "Eleti-Ọfẹ".

Mo dupe fun aye ti ẹ gba mi.

Emi ni,

Kaduna Olubọ

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

(LATI ỌWỌ AYILUKA)

## Elewon Ti-O-Nsunle

Oju mi ri nkan ni Ibadan ninu ọsẹ ti o kọja: awọn ọlọpa ha mi ni iwe-ihamọ (restriction order) ni ile ti mo de si. Mo bi wọn lere wipe kinni mo se. Nwọn ni emi na jẹ enikan ninu awọn ti o nyọ awọn ara ilu lenu nitorina ni awọn nilati ka mi mọ awọn ẸLẸWỌN TI-O-NSUNLE. O jẹ mọ wipe ọrọ na ko tete ye mi? A fi igbati mo de Teṣọn WASINMI leti Abẹokuta.

Awọn Ọlọpa miran tun da mi duro ninu moto ti mo wa; nwọn ni mo jọ ọkan ninu awọn iranṣẹ - ijọba (ti ẹ npe ni Minisita) ti nwọn ni ki awọn ko lọ fi pamọ fun igba diẹ.

Nitotọ ibatan mi wa ninu awọn oṣelu l'Eko ati ni Ibadan, ṣugbọn ti nwọn ba fẹ sọ mi di ẸLẸHA ỌSAN GANGAN ki nwọn jọwọ ki nwọn mu mi lọ si Eruwa, tabi Shaki tabi Oke-Iho nitoripe mo fẹran ẹran-igbẹ pupọ pelu amala ati ọbẹ gbẹgiri; mo si mọ wipe nwọn mọ ọbẹ yi nṣe ni awọn ilu ti mo daruko yi.

Lẹhinna awọn Ọlọpa ni lati jẹki nma ka iwe mi lasiko-lasiko, nsi ma mu oti-biya mi kara-kara, iyẹn bẹ, nwọn si ni lati gba i laye ki awọn obinrin ẹlẹyinju-ẹgẹ lati Eko ati Ibadan ma wa ki i nitoripe awọn ti o fẹran mi pọ diẹ ninu wọn.

ILE ỌBA T'OJONA

Mo tilẹ gbọ wipe nwọn ti fi ọmọge kan da ọkan ninu awọn Minisita wa ti nwọn mu lọ si ile-ipamọ na lọla. Ẹnyin na ko wa ri wipe ile-ọba ti o jona ẹwaa ni o busi i?

Mo de ọdọ ọkan ninu awọn ti nwọn fi iwe-ofin semọ'le na ni Ilesha, nṣe ni nwọn nwole fun un bi Ọba ori-itẹ. Mo tun de ọdọ ẹlomiran l'Oshogbo, nṣe ni awọn ara ilu ibẹ dal'ọla pelu orisirisi nkan.

Mo gbọ wipe Baba Ogbomọsho paapa njiṣẹ turẹ, bi awọn ara Oke-Ijeru ti nwa ki i, ni awọn ara Oke-Elerin si nfi ẹsẹ palẹ; bi Ọmọdele ti nṣe, ni o nṣọ. Ẹnikan nikan ni mo gbọ wipe ko si nile, sugbọn mo mọ wipe arabinrin nako ni ibikan re ju ilu Igbajọ lọ. 'Torera, Ọmọ a-fi-agogo-mu-ẹmu, ki o tọju Ladoke o!

Ẹ ko wa ri bi aiye ti ri nisisiyi enyin ara mi? Ọmọ-ẹru di ọmọ-ile, Ọmọ-ile di ọmọ-ita; ẹniti o ba tun ku ki nwọn ṣọ'ra, aiyẹ ko si fun ẹnikan. Ẹniti o ba sọ otitọ ni ilẹ yio gba. O ilọ ni yio lẹke.

IYALODE ILE-MOSU KỌ'WE

"Ṣe mo sọ fun nyin ninu iwe mi ti ọsẹ keji ti o kọja wipe awọn obinrin "ile-mosu" pọ nilẹ yi nisisiyi? Ọkan ninu wọn ti o ri iwe irohin ti mo kọ nipa wọn ka kọ'we kan si mi lati Ọbẹlẹ Onẹwala ni Suru-Lere. Mo fẹ ki ẹ ka iwe rẹ na ki ẹ fi eyi kọ'gbọn. Iwe ti "ile-mosu" ko na niyi:

"Ọgbẹni Ayiluka tabi bowo ni nwọn ti npe ọ? A ri iwe ti o kọ ti o fi npẹkan wa ka. Awa ko mọ wipe wiwa ti o wa si ile wa nijọsi, ti o ni nwọn tan ẹ mẹ lati ka enia, ti o si nbi wa bi ile-ọkọ wa ni a wa tabi ile obi wa, ebu ni o jẹ ba wa sinu iwe yin na

"A fẹ ki o mọ wipe ki se idunnu awa na lati fi ile baba wa se ile-ọkọ, bi ko ba nidi obinrin ko ni jẹ Ikumolu. Bẹ bi enia ko ba lori ọkọ a ni ori ale. Ọkọ atata paapa kosi nilu mọ, awọn fawọraja lo pọ.

"Tabi o le ri ọkọ atata fun wa? Ti a ko ba si nile ọkọ iyẹn ko wipe ki a rin pelu idoti, iyẹn kosi wipe ki a lọ se bẹbẹbẹ lori kerem.

"Bi a ba wadi rẹ daradara, boya iwọ paapa ko ni iyawo kan nile, fawọraja ni o mba kiri. Ti o ba tun ba kati-kati de ọdọ wa, wa gba abuku".

ỌRỌ KATI-KATI

Mo dupẹ lọwọ Iyalode "Ile-Mosu" ti o ni ọrọ kati-kati awọn ko gbọdọ gbọ mọ lati ọdọ mi, atipe se mo le ba awọn rọ'kọ atata, atipe boya emi paapa ko tilẹ ni iyawo nile.

Emi kii se ẹni abuku, ẹni ti nwọn mbukun ni mi; emi na ti ni'yawo ni ile ri nibiti mo gbe nṣe Ayiluka kakiri ni o se komi silẹ. Ṣugbọn bi Iyalode "Ile-Mosu" ba le ba mi ri iyawo atata emi ko kọ rara. Opo ti o mọ ọbẹ se daradara ni mo fẹ, emi ko fẹ "Ile-mosu" iyawo oni moto bọlẹkaja ti yio ma wipe "emi ko ba alakọsu ku, ti ngo ba elewura lọ ọrun". Ọrọ pọ nibe.

## Alufa Sosi Kan Pe Awon Ijo Re Lejo Si Kotu

(O bẹrẹ l'oju ewe kẹta)

on ko sebi rara. O ni nitotọ ni on fi owo awọn ijọba kọ ile-iwe kan ṣugbọn pelu owo awọn ẹgbẹ kan ni Ṣọṣi na ni.

Alufa na ni nitotọ ni on yan awọn akapo bi eni mẹrin, ṣugbọn iyawo on ko si ninu wọn. Nibiti o gbe ti nsọ eyi ni Ọgbẹni D.O. Omisore, lọya ti awọn ẹlẹjọ rẹ gba bẹrẹ-si ṣe ikilọ fun un wipe ki o ya pe ẹja irọ. Lọya on alara paapa, Ọgbẹni Olu Ayọọla ni ti ko ba sọ [illegible] eyiti o yẹ ... ninu ẹjọ na.

Adajọ kotu na si ti ọsu ẹjọ lati gbọ iyoku ọrọ na siwaju.

## Bolu Agba W'orun



Douglass Carr ti ise Balogun awọn agba bọlu ti a nwo ninu aworan yi, ni o gba bọlu kan ti Saeed Ahmed ti ilu Pakistan ju ni agba w'ọrun-bẹ l'ori nigbati bọlu na lọ s'oke ti oju fẹrẹ ma le ri mọ, ki o to pada wa silẹ.

# Awon soja ologun

## Njaiye Ni Ibadan

IBADAN—Ogunlọgọ awọn sọja ti awọn Alakoso Ijọba Apapọse fi ase pajawiri muwa si ilu Ibadan lati Kaduna wipe bi ya ija-igboro le bẹ silẹ nitori edeaiyede ti o wa larin awọn oselu, ni nwọn ti bẹ sita, ti awọn na si njaiye fa'ala.

Ni ojo Satide ti o koja yi ni awọn ara ilu to mọ wipe nitoto ni awọn Ijọba Apapọse ko awọn sọja wọ 'lu tobẹ, nitoripe lati kutukutu owurọ ni awọn sọja yi ti ko sinu asọ-ogun wọn, ti nwọn di amure, ti nwọn si nwọ kiri ilu tobẹgẹ ti tọmọde tagba fi mbere lọwọ ara wọn wipe, "ogun Jamani miran tun de ni tabi kinni awọn sọja yi wa ṣe ni Ibadan to yi"?

Gbogbo ile-ọja ti o wa ni Dugbẹ, Gbagi ati Ogunpa ni nwọn nwọ ti nwọn si nra ọja ti nwọn yio lo ati awọn oniruru nkan ti nwọn fẹ fi ranṣẹ si awọn iyawo wọn ni'le.

---

## Ijoba Ila-Orun Fe Fi Kele Gbe Awon Adamodi Dokita

ENUGU — Laipẹ yi ni Minisita Alamojuto Iṣẹ Ilera ṣe ikede kan nibi aṣeyẹ kan ti nwọn pe e si, wipe Ijọba awọn ni Ipinlẹ Ila-Orun ngbaradi lati fọwọ si iwe-ofin kan ti awọn o fi ni agbara lati le ma da sẹria fun awọn adamodi dokita ti o pọ jaburata ni Ipinlẹ na.

Minisita na tun ṣe alaye wipe nigbakugba ni irohin nkan awọn wipe awọn oni-wayo dokita yi ojojumọ ni nwọn npọ si, ti nwọn si nṣe awọn ara ilu ni ijamba, ti nwọn si npa tọmọde tagba bi ẹni pa ẹran.

Minisita yi ni ti iwe-ofin na ba ti jade, a fun awọn ni agbara ni Ipinlẹ awọn lati sọ ẹnikẹni ti awọn ọlọpa ba ti mu, ti nwọn si dalẹbi, lati sọ sewọn ọdun gbere (life imprisonment) ki o le jẹ ikilọ fun awọn ẹlomiran ti nwọn ti mura tan lati maṣe iru iṣẹ buruku bẹ.

---

## OBINRIN KAN DI MINISITA ALABOJUTO ETO IJOBA NI SARO

FREETOWN—Inu ogunlọgọ awọn obinrin ilu Saro (Sierra-Leone) ni o dun nigbati nwọn gbọ wipe Olotu Ijọba ilu na yan ọkan ninu wọn ni Minisita Alabojuto si eto Ijọba. Orukọ Obinrin ti nwọn dalọla na ni Oloye Ella Koblo Gulama. On si ni obinrin kinni ti nwọn yio kọ yan si iru ipo bẹ ẹ ni Iwọ-Orun Afrika.

Iṣẹ alabojuto iṣẹ awọn tiṣa ni obinrin yi nṣe tẹlẹ, nwọn si fi jẹ oye pataki ni ilu rẹ ni nkan bi ọdun mẹsan sẹhin atipe akọkọ wọ igbimọ rẹ kọ ni eleyi; o wa ninu awọn ti nwọn yege idibo ni ọdun 1957, o si ba nwọn lo ọdun marun gbako ni ile Igbimọ ki nwọn to tun yan an ninu ọse ti o koja yi.

---


# OKUJA WO'LU

NIGBATI ỌJA KO BA TA, TI ẸNITI O RA ỌJA KO TA EYITI O RA, BAWO NI YIO ṢE LE RA OMIRAN. EYI NI OGUN TI ONIṢOWO LE ṢE

TI ỌJA LE FI MA TA

BI IṢU AKARA GBIGBONA.

POLOWO ỌJA RẸ SINU ELETI—ỌFẸ

---

# ELETI - OFE D'ARABA

# Ema Ka Iwe Irohin Eleti - Ofe

**Ti o kun fun Irohin Aladun L'osose**

# New treatment for Acute Malaria

LONDON - The successful use of treatment with an artificial kidney in acute cases of Malaria and blackwater fever was reported in last week's "British Medical Journal."

Professor A.W. Woodruff, Wellcome Professor of Clinical Tropical Medicine at the University London, and Air Commodore R.C. Jackson of Princess Mary's R.A.F. Hospital at Halton, point out that acute renal failure is dreaded consequence of severe malaria and blackwater fever.

### Kidney

Discussing what they believe to be the first ever use of an artificial kidney in the treatment of patients with malaria renal failure they say that this modern therapy gives an improved chance of survival.

The two doctors state that all the cases had omitted to take malaria prophylactics; they stress that everyone spending even 24 hours only in a malaria area needs to take one of the standard malaria preventatives.

## British Ship "Discovers" Underwater In Africa

LONDON — A Royal Navy survey vessel has returned to Britain with evidence that the east coast of the African continent may extend underwater for nearly 1,000 miles from the existing coastline.

The vessel, H. M. S. OWEN, has been engaged on survey work in the Indian Ocean as part of the British contribution to the two-year international Indian Ocean expedition sponsored by the International Council of Scientific Unions and by U. N. E. S.C.O.

The Admiralty announced recently that H. M. S. OWEN, which sailed from British last September for the first of five seasons in the Indian Ocean, reports that her survey work has revealed an off-shore zone 200 miles wide and extending about 2,000 miles from Madagascar to Socotra island. The characteristics of the zone suggest that it may be underlaid by a wedge of sedimentary rocks several miles in thickness and effectively extending the continent of Africa.

## Queen Opens New Science Building



Her Majesty Queen Elizabeth II looking through a high-powered microscope in the physics laboratory of a new £430,000 science block at Westfield Ladies' College London, recently. Her Majesty opened the new block and named it Queen's Building".

## Ghana Plans To Buy Ships From Japan

NAGUSAKI — Japan is among some industralised countries from which Ghana Plans to buy ships, Mr W. Baidoe - Ansah, Ghana's Ambassador in Japan, disclosed during a discussion with the management of the largest ship building yard in Japan.

Mr Baidoe -Ansah, who was on official visit to the Southern Island of Japan said the final decision on the purchase would depen on certain factors, including quality and credit facilities.

### AID

Later, accompained by his entourage, he visited the Yawata steel works at Fukuoka where the management promised to give Ghana assistance needed to establish a similar industry.

Mr Baidoe -Ansah was shown round the works the biggest steel manufacturing factory in Japan, by the chief engineer.

The factory, established by the Japanese government in 1900 but now a private company produces 25 per cent of Japan's steel.

Mr Baidoe - Ansah recommended Ghanaian manganese ore as one of the highest quality in the world.

## Omo Araiye Ko Feni F'ere

(O bẹrẹ loju ewe keji)

ẹgẹẹco mẹrin ati ati ada fun awọn ugbado wọnyi w fun lati ma sun jẹ. Inu aginju igbo rere ni wọn gbe lọ, aṣọ meji pere ni wọn fun kun awọn ohun elo rẹ, wọn wa fi on nikan sibẹ pẹlu iwa rẹ. Ninu i g b o yi on ni kan ni alaye ẹda asi tun fi ẹiyẹ abami kan: ti o ba ti di ni owurọ kutukutu a ma ke bayi wipe "afi Ọlọrun Ọba nikan lo pe julọ ninu awọn ẹda" asi tun ma wi bayi wipe "ẹni jiya ni jọrọ". Ọkunrin adẹtẹ yi larọ-larọ a woke a wolẹ a bu puru sẹkun, ohun kan a si ma ti ẹnu rẹ jade wipe "aṣe bi emi ko ba ku, ngo,wa di baba, baba nkan lẹhin wa ọla" Adẹtẹ yi nfi han wipe ireti mbẹ lẹhinwa ọla, adẹtẹ tun nfi han wipe on ni igbọkanle si Ọlọrun Ọba,

Ẹo ri iyoku itan yi ni ọsẹ to mbọ.

---

## Awon Ebi Elliott Seye Fun Omo Won

Irohin ko to afojuba ni ẹyẹ ti awọn ọmọlẹbi Elliot ti Olowogbowo ṣe fun ọkan ninu awọn ọ m ọ wọn kan obinrin ti o de lati ilu Oyinbo lọsẹ t i o koja ti orukọ rẹ njẹ Iyafin Ọmọlolu Ogundipẹ ( ọmọ King) ni 8, Oke Olowogbowo, l'Eko.

Lati ki ero ilu Oyinbo n a p e "o ku-abọ", gbogbo awọn gbajumọ e n i a lọkunrin a t i lobinrin n i nwọn mu moto-ayọkẹlẹ lọ pade rẹ ninu ọkọ Apapa. Lẹhin e y i gbogbo awọn ti o w a s i ibi-ẹyẹ n a wa ba ero ilu Oyinbo na lọ si Ṣ ọ ṣ i Olowogbowo fun isin-idupẹ.

Bi nwọn ti ṣe isin idupẹ y i t a n n i gbogbo awọn ti o wa si ibi aseyẹ na ba gba Oke Olowogbowo l ọ nibiti awọn ọmọ-lẹbi Elliott, King ati Macaulay bẹrẹsi fi awọn nkan jijẹ ati nkan mimu tẹ olukuluku a w ọ n ti o wa sibẹ lọrun.

A ki Ọmọlolu ku abọ' Tayọ ati Kofo, ẹ ku aṣeyẹ, Ọgbẹni Ogundipẹ, ẹ ku afojuba !

---

## ELETI - OFE DARABA

---

Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company. 28 Kosoko Street Lagos Box 467 Phone 23378. Olola L. A. OJO. 12 Inabere Street, Lagos.

# Odomo'binrin Jare Baba Re Ni Kotu Alikali

KADUNA— Ninu Kotu Alikali Waje nilu Kaduna ni ọdọmọ'binrin kan Malama Fatima Audu kọwe ẹbẹ si Kotu wipe ki Kotu kọ fun baba on, ki o maṣe fi on fun ọkọ ti ewu ti gba gbogbo ori rẹ kan, arugbo ọkunrin onigbajamọ, Malam, Dandaura Wanzami.

Kotu gba ẹbẹ rẹ, wipe ki baba rẹ jẹki o fẹ ọkọ ti o wu lati fẹ, Onigbajamọ miran ti o njẹ Malam Muhammadu Jinjiri. Gbara ti Onidajọ Malam Abubakar ti se idajọ'na ni M a l a m Muhammadu, Onigbajamọ ti bọ siwaju adajọ, o si san pọnun mẹjọ ti nwọn ni ki Malama Fatima dapada fun Malam Dandaura ti o kọ sile.

Malama sọ wipe Malam Dandaura ti dagba ju fun on, on ko si mọ idi rẹ ti baba on fi nfẹ ki o jẹ ọkọ on. Malam Muhammed jẹ ọdọmọde, o si wu on lati fi ṣe ọkọ.

Baba rẹ, Malam Audu sọ fun adajọ pe, o nidi ti on ko fi fẹ ki Fatima fẹ Muhammadu. Onidajọ Kotu, Malam Abubakar sọ wipe ofin ẹsin Musulumi ko gba ki enia fi ọmọ rẹ fun ọkọ ti ko tẹ ọmọ na lọrun. Nipa bẹ, nko le ṣe nkankan ju ki ngba ki ọmọ na lọ fẹ ọkọ ti o ba wu lọ.

---

## Oyinbo Kan Ni Oyinbo Ti O Ba Fe Joko Ni Ilu Yi, Ki O Mase Fe Obinrin Enia-dudu.

(O bẹrẹ loju ewe kini)

Ọgbẹni Tate ni awọn ẹnikan ti nwọn sunmọ awọn oṣelu ṣe ofofo fun on wipe, lọjọ ti on ti gbe ọmọ Ibo, Philomena, ti on fẹ sile ni iyawo ni awọn ti o yọ on niṣẹ, ti ni on sinu, ti nwọn si nwa bi nwọn o ṣe wa on kuro nilẹyi.

O ni ọjọ ti a gba ominira nilu yi kotilẹ jẹ nkankan fun awọn kan ti nwọn nṣe ojusaju. O ni ju gbogbo rẹ lọ, on fi iyawo on ati ọmọ rẹ si abẹ-abo awọn ọrẹ enia-dudu ti on ni, ti nwọn si r a n on lọwọ pupọ nigbati wahala na de ba on.